# AKI ISORE ERO K'AYO ERO NRE'LE RE BODOLA



*AWOGBA Omode fun Giri, Eyi, Hiku-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*

ELETI OFE
A-NJU-WON KO ŞE WI L'EJỌ

*TO CLEAR*
*Gents Suede Court Shoe, Brown, Black & Grey*
*Before 50/- Now 42/6d*
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
*10A Moloney Bridge St.*
LAGOS.

VOL. VIII No. 455. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 18, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## AKI ISORE ERO K'AYO



ALAIYELUWA ỌBA OBINRIN ATI ỌLỌLAJULỌ ỌKỌ RẸ.

Gbolohun oke yi ni o wa si ọkan wa wipe "Aki isọrẹ ero k'ayọ, ero nre'le rẹ b'o dọla" nigbati a ri ogunlọgọ ailekatan enia l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde ati agbalagba, ti gbogbo nwọn nho iho ayọ ati ilẹ si Alaiyeluwa ọba obinrin ilu Oyinbo Gẹsi ati ọlọlajulọ ọkọ rẹ ti nwọn ti fi ọla wọn wa bẹ ilu wa Nigeria yi wo, ti nwọn si npada lọsi ilu Oyinbo.

Gẹgẹbi ero ti ọpọ enia ni ati ifẹ ayọ erin musẹ ti Alaiyeluwa ọba obinrin pẹlu ọlọlajulọ ọkọ rẹ fi ma nki awọn enia mu ki a ma fẹ ki nwọn fi ilu wa sile mọ

Elomiran fẹrẹ le ma ko wipe ni ọjọ wo ni on tun le fi oju ri bi iru awọn Eni-aiye-nfẹ bayi ni igbesi aiye on? gbogbo itara wa wọnyi je eyiti Alaiyeluwa Ọba obinrin ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ papa fi ifẹ won han si awa enia abẹ Asia Ijọba rẹ ti o jẹki ifẹ ati maa bu ọla ati ọye ti o tọ to si yẹ gbojikan lori ọkan gbogbo enia patapata.

E wo aworan inu iwe wa yi bi awọn eni-iye-nfẹ na ti nju ọwọ fi d'agbere fun ọpọlọpọ enia, Oyinbo, enia dudu, ọmọde ati agbalagba ti o şin si ọna nibati awọn wọ Mọto Ayọkẹlẹ wọn tọ si ni ile Ọba (Govt. House) titi ti nwọn fi wọ ọkọ ofurufu ni Ikẹja.

Ibudo Ọkọ ofurufu ni Ikẹja ni ki o wa wo awọn ọlọla enia ati awọn saraki ilu Eko awọn Minisita pẹlu awọn oşelu ti nwọn ba Alaiyeluwa de idi Ọkọ Ofurufu, awọn ijọ ijọ Ọlọpa Ọba duro s'ọtọ, ijọ ti awọn Şọja bakanna ni, Gomina gbogbo-gbo pẹlu awọn isọngbe rẹ duro giringiri lati ri wipe Alaiyeluwa ati Ọlọlajulọ Ọkọ rẹ wọkọ ni alafia kuro nilu wa nihin.

Ki o wa wo bi ilu Eko ti nlọ rọnyin-rọnyin fun ere ayọ idunnu wipe alafia ni Alaiyeluwa Ọba obinrin ati Ọlọlanla ọkọ rẹ ba de ilu Nigeria wa yi ni gbogbo igboke-gbodo rẹ ti o si fi nşe bẹwo yika gbogbo ipinlẹ Nigeria bi ilu Oke-Ọya (North) Ila Orun (East) ati Iwọ-Orun (West) ti o tun pada silu Eko (South) ti ko si ikọ, ti ko si si amodi ogo nla ni eyi jẹ fun wa nilu Nigeria bi orile-ede.

Ariwo nla gee wipe o digba oşe alafia ni ẹo de'le ọkọ arefo o si gbogbo enia nko.

## Ilu Ibadan Gba Ọba Elizabeth Keji L'alejo

IBADAN—Ni agogo meji abọ ọjọ Satide, ọjọ kọkanla oşu keji odun yi ni Ọba Alaiyeluwa Elizabeth keji, ti gbogbo oril-ede Gẹsi pẹlu ọkọ re Mọgaji ilu Edinboro bẹ ilu Ibadan tişe olu-ilu ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun wo. Bi oko oju irin ti o gbe wọn wa ti nsunlẹ ni Gomina ọlọla John Rankine fi tọwọtọwọ ki wọn ti won si gba lọwọ.

Lẹhin eyi yi ni omidan Awolọwọ gbe ododo arẹwa fun Ọba na Gomina si fi awọn jankanjankan ipinlẹ yi han Ọba. Niun awọn ti a fi han ti Ọba gba lọwọ Ọlọla oloye Ọbafemi Awolọwọ, Olori Onidajọ Ọlọla A. A. Adamola Igbakeji Gomina ọlọla T. M. Shankland, Ọba Adesọji Aderẹmi, Ọlọla R.A. Doherty Ọba Akezua ti Ibinni, Ọba Ọlagbegi keji ti Ọwo, Ọlọla oloye F.R.A Williams, ọlọla C. D Akrah, Ọlọla A, m. A. Akinloye, Ọlọla S. O Awokoya, Ọlọla F .O Awosika Ọlọla E. A. Babalọla, Ọlọla oloye Enahoro, lọla Ighodairo. Ọlọla oloye J. F. Odunjọ Ọlọla D. C Osadebay. Olori Alufa A. B. Akinyẹle. Olubadan I. B. Akinyẹle wakọ Ọba M. Akagbosu ati Oluşe ọkọ Ọba E. O. Ọnabanjọ.

Lẹhin eyi ni Ọba na kọja larin ọmọ ogun ti ilu ati tere ndun yungba yungba. irọlẹ ọjọ kanna gongo sọ ni gbọngan Ipinlẹ Iwọ-orun ni Agodi, nibiti Ọba obinrin na wọ aşọ to minringindin to si fi okuta olowo iyebiye toju wura lọ şe ori lọşọ. Nihin ni olori alaşẹ Ipinlẹ Iwọ-orun Ọlọla oloye Awolọwọ gbe iwe ikini kabọ le lọwọ Oba si fesi togbadun

Lẹhin eyi ni Ipinlẹ Iwọ-Orun fun Ọba ati Ọkọ rẹ ni ẹbun meji Irukẹrẹ ti a fi ilẹkẹ olowo iyebiye gba nidi fun ọba Abẹbẹ ti a dabira si idi rẹ fun Ọba ati Ọkọ rẹ Timutimu ti a si fi ilẹkẹ oniyebiye şe ọna si fun ọkọ Oba, Ọmọ Langii (Ibeji) ti a gbẹ ni

(Wo yoku loju ewe kejọ)

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited.**

Ọna tare ti enia legba lati
di onişowo nilẹ Nigeria wa,
ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Enikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimọye awọn onişowo ilẹ Nigeria lara,
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IŞẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AŞOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## ỌBA OBINRIN N'ILU NIGERIA



Aworan ti ẹ nwo yi niti Alaiyeluwa ọba obinrin Elizabeth keji pẹlu ọba Adeniji Adele, keji ti ilu Eko ti iṣe Alakoso ile Igbimọ olutọju ilu Eko ni gbangba - teju ayida-ọna ni Ita Yaba ti a npe ni Yaba Round-about.

Nibẹ ni ọba Eko ti duro pade ọba obinrin ilu Oyinbo pelu ọlọlajulọ ọkọ rẹ ti ọba tayọtayọ ki nwọn ku abọ - ninu ọrọ ti Kabiyesi sọ ni ọjọ na ni o m'ẹnu ba ọjọ ti aṣia Ijọba Gẹsi kọ fẹlẹlẹ ni agbala ọba Eko ni ìgba Ijọba rere ti ọba obinrin Queen Victoria onipa'te. Eyi je [illegible] August ti ọdun 1861. [illegible]

Ọba Adele [illegible] tẹsiwaju wipe [illegible] pẹlu Ijọba [illegible] ọpọlọpọ anfani [illegible] si l'ọna owo [illegible] oni [illegible] wipe awọn [illegible] ilu ayọ [illegible]

awọn ẹniti o ti ni idapọ pẹlu Ijọba nla ti Gẹsi ti o fẹrẹ to ogorun ọdun s'ẹhin.

O si dun mọ wa gidigidi gẹgẹbi iyẹsi ti ẹ ṣe fi gba wa l'alejo tọwọ-tẹsẹ a si ni ireti wipe wiwa mi ati Ọkọ mi si ar[illegible] yin y'o jẹ ohun ti y'o tubọ so okun Nigeria mọ Ijọba nla ti ilẹ Gẹsi.

Emi ati Ọkọ mi ki yin, ṣe alafia ni a ba gbogbo ẹ yin enia mi to mbẹ ninu olu ilu Nigeria.

ESI IJỌBA OBINRIN FI NIPA SỌKI

Oni [illegible] a de si Nigeria lati wa dun [illegible] awọn nla ti o mbẹ ninu Olu-Ilu na

---

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun

## Isinku Olojede Oyedirin Odunmarun

Irohin ko to afojuba ni ọjọ kẹfa oṣu kini ọdun yi ni ilu Ejigbo ti a ṣe oku Ologbe Alagba Ọlọjẹde Oyedirin Odunmarun.

Baba yi di ẹni ogoje ọdun ki o to fi aiye silẹ lọ jẹ ipe Ẹlẹda rẹ. Ni akoko aiye ti Ologbe yi, o jẹ oye Ọmọlẹbi Elejigbo ti a npe ni Odunmarun ni eyiti gbogbo awọn enia si gbadun akoko tirẹ. Ologbe alagba Ọlọjẹde Odunmarun jẹ ẹnia rere ati olotitọ nigba aiye rẹ, o si jẹ babalawo pataki, bẹni on ni a si fi ṣe alaga awọn igbimọ ti ibu iye le owo ori ni Ejigbo. O fi awọn ọmọ rere silẹ lati tun ẹhin rẹ ṣe.

Ni ọjọ isinku Ologbe yi ni atẹ sinu Posi ti a fi jigi kan ti o nsi ndan gbinrin Ọpọlọpọ to fi oju kan pos, olowo iyebiye yi ni o ki aje ku ikalẹ. Ki a to pari isinku yi ni awọn ọmọloku ti bẹrẹ si da malu lagbalẹ bi ẹni pa adiẹ. Ẹran pipa ko niye titi o fi di ọjọ kẹjọ oṣu keji ọdun ti a fa agọ egun baba yi jade.

Nigbati ao ṣe o k u y i ni gbogbo ọmọlẹbi Oloye Odunmarun awọn Ijoye ilu bi Osholo, Ejemu Ọ y ẹ, Alawe pẹlu awọn pataki miran ati awọn agbagba ilu gbogbo awọn ẹlẹgbẹ inu ilu lorisirisi ati awọn ọrẹ larin ilu ati okere pejọ lati ṣe oku nla yi. Ọjọ nla ma ni ọjọ yi o ninu ilu Ejigbo, A bẹrẹ ijo ninu ile igbimọ ilu (Council Hall) ti Ejigbo lati dede agogo marun irọlẹ titi di agogo kan oru, Oti oyinbo olowo iyebiye ti o sofo sinu ile yi koni iye, bakanna si li onjẹ ati ẹran ti awọn enia jẹ ni ajẹti, Bi awọn enia ti njo ni awọn ọmọ oku bẹrẹ si fọn owo bi ẹni fọn erupẹ. Ayọ gba ọkan ẹnikẹni fun ẹhin baba ti o dara to bayi Bi a ba wa ni aiye, ẹ jẹki a ma gbadura ki a ri awọn ọmọ ti o yanju tun ẹhin wa ṣe.

D'ẹ ninu orukọ awọn orisirisi ẹ g b ẹ t i o w a niwọnyi:- Egbe Kafinta, Ẹgbẹ Imọlẹ. Ẹgbẹ Iyaniwura, Ẹgbẹ Jibi, Ẹgbẹ Bọmọdeoku, Ẹgbẹ Emilere, Ẹgbẹ awọn Babalawo, Ẹgbẹ awọn Elegungun, pẹlu orisirisi egun nwọn gbogbo, Ẹgbẹ Ejigbo Parapọ, gbogbo awọn Ijoye Ilu Ẹgbẹ Mọle-bi ọ b a, Ẹgbẹ Oniburẹdi, Ẹgbẹ Ọmọnigbẹhin aiye Ẹgbẹ Ọbanisọla, Ẹgbẹ awọn Lawani Nomba Ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ Ijọba I b i l ẹ Ejigbo.

Ninu inawo oku yi gbogbo a w a ọmọloku d u p ẹ gidigidi lọwọ baba wa Elejigbo fun inawo ti o ṣe fun wa bakanna a ni a si tun dupẹ lati ọdọ baba wa O sholo, Alaga kotu ibilẹ, Ejigbo ati awọn ọrẹ lorisirisi ti o ṣe inawo fun nigba oku baba wa yi.

Ki Ọlọrun jẹki iru bayi jinna si ara wọn – Amin.

Orukọ awọn ọmọloku ti o ṣe bẹbẹ nibi inawo baba yi niwọnyi:- Fakunle, Busari Fadoyin, Ọ l a d a y ọ, Alari, Ọlajọkẹ. I f a k o r e, Oyeyinọla Daniel Akinboye Ejiwoye, Ọwadare. Jenrọla ati Ọlagbende. Ki Ọlọrun jẹki ẹhin baba dara o Amin.

## Ole Jija Ni Ise wa

IBADAN. Gbolohun o k e y i "Ole jija ni iṣẹ wa," ni gbolohun to jade l'ẹnu ọdaran keji ninu awọn ogbonkangi ọ l ọ s a kan ti awọn ọlọpa ọba r a m u l'ọna ilu Oshogbo nigbati awọn de ayipo-ọna ni Agodi. (Agodi Round-about.)

Gẹgẹbi ọrọ na ti lọ niyi:- Nigbati awọn eru'ku na nlọ ni ọlọpa fura siwọn, o s i s e wọn wo, nibiti ọlọpa ti nyẹ ẹru wọn wo, wọn ri ake kekeke, I w o kan, olulu ti awọn fi atu akaa bi iṣo tabi ki a fi da pako lu ati awọn kọkọrọ meji ninu apo kan.

Ẹnikini ni Audu Angu, ti o pe ara rẹ ni O n i ṣ ẹ - ala'gi (Sawyer) Isa Fulani Yọla ti o sọ wipe iṣẹ Saji - mejọ ninu Sọja atijọ ni on, Mọmọ Zaria, ti iṣe ọdaran kẹta ọkan ninu wọn ti orukọ rẹ njẹ Adon Zaria ni o sa ti ọwọ ko iti tẹ.

Nigbati nwọn mbere ọrẹ lọwọ ẹlẹgiri wọnyi ni kọtu onireke, Mọmọ Zaria ko fi ọsi kan ju "babu" ibabu" lọ, ṣe ẹ wa ri ọdaran keji iyẹn ni o sẹ wipe on ko ni fi ẹpọ bo'yọ o sọ fun Adajọ wipe ole jija ni iṣẹ awọn Ogbonkangi ole ni si ni awọn ṣe.

Adajọ fi idajọ di ọjọ kọkandinlogbọn osu yi.

# IROHIN ILU OYINBO

## IPENIJI NI IGBE-AIYE JẸ FUN OLOYE TI EDINBURGH

Lati Ọwọ Ogbeni Dimbleby,
Ọjọgbọn Ile Ẹrọ Gbohungbohun Ile Gẹsi

Gẹgẹbi ọrọ Ọgbẹni Dimbleby, Ọba nikan le tente lori afin, gbogbo awọn yioku patapata ti o fi mọ awọn aya rẹ ni wọn wa ni abẹ apoti itisẹ rẹ, ti imulẹ Ijọba ṣi de.

Ti a ba wo ipo ti oloye ti Edinburgh ti wa lẹhin igbati Ọba Elizabeth keji ti de ade, ati awọn iṣẹ pataki ti o ti ṣe ni idiie Ọba, a nilati ma ranti wipe sibẹsibẹ ọkan ninu awọn enia ti o wa ni abẹ abo ati idari Ọba ni o jẹ.



DUKE OF EDINBURGH

Ṣugbọn lọna miran ọkọ ni o jẹ fun Ọba obinrin Elizabeth, nibi ni iyi rẹ wa gbe farahan. O wa ni ipo ti o ni ogo gẹgẹbi ẹniti o le ba awọn enia sọrọ nigbakugba lai si idiwọ, lati ma gbọ ati lati ma mọ ero wọn; on si tun ni ẹnikanṣoṣo ti o ni anfani lati ma ba Ọba obinrin ti iṣe iyawo rẹ sọrọ ni ikọkọ laisi ifoya.

### AGBARA IWA RẸ

Nipa oloye yi ale sọ wipe gẹgẹbi ọm'ọba Phillip o bẹrẹ iṣẹ titun o si ni ibori daradara ọkọ kọkan fun ipinlẹṣẹ iṣẹ na.

Biotilẹjẹpe ọmọ alade ni, a kọ gẹgẹbi awọn ọmọ mẹkunnu ni ile ẹkọ ti o wa ni ilu Dartmouth. Ẹniti o jẹ alakoso ile ẹkọ awọn ọmọ ogun oju omi yi jẹ alakikanju amoye enia, ninu gbogbo nkan miran o kọ awọn ọmọ rẹ bi a ti ngba iṣẹgun ati bi a ti nyọ ninu ibori. Iṣẹ ọwọ lile jẹ ọkan ninu iṣẹ ile iwe yi, pẹlu ilọsiwaju ninu iwa rere ẹmi fun iṣẹ ati ọkan iṣoro.

Gbogbo ohun ti o ti ṣẹlẹ bi ọdun meji gbe iṣẹ ti oloye yiti ṣe yọ o dabi orisun agbara ati iṣiri fun Iyawo rẹ, Elizabeth keji, pataki julọ nigbati a ba wọ irin ajo kakiri ti o si npade ọpọlọpọ enia.

Wahala irin ajo ti iyawo rẹ ṣe yipo aiye bi ọdun meji ano sẹhin iba ti gun rẹgi tobọ ti ko ba si tirẹ. Ẹniti o ba si ri aworan ti wọn ya ni akoko irin ajo yi yio mọ bi agbara ojiji, ati ẹrin musẹ ti oloye yi nrin si awọn enia ti mu ki ariya tubọ larinrin dada si.

Bi o ba sọrọ ni gbangba ẹwẹ gbogbo iwadi ọrọ rẹ ni ma ni ipilẹ ti o jinlẹ.

O ni igbagbọ ninu ki oju rẹ mọ ilẹ danju ọrọ ti a ba gbe siwaju rẹ, ki si fẹ ṣe baba ẹgbẹ nibiti wọn ko ba ni fun laye lati ṣe akitiyan ninu ọran wọn. Bi apẹrẹ nigbati o pinnu lati pe ipade awọn aṣoju ilẹ Gẹsi ati awọn ilẹ ti o wa ninu ẹgbẹ Commonwealth lati ṣe aṣaro lori iṣẹ awọn enia ni agbegbe wọnyi lori iṣẹ onisowo, ohun ti o kọ ṣe ni wipe o pe agbajọ ẹgbẹ onisowo kan si afin ọba lati ba wọn jiroro lori ọrọ ti wọn fẹ sọ nikọkọ laifetisi atako awọn enia lẹhin na.

Iru nkan bawọnyi ti fun ọkọ Elizabeth keji ni anfani lati fihan awọn enia wipe on ni ero nigbagbogbo lati lo ipo on fun rere awọn enia laifi eti si awọn ti o ntako. Ifẹ rẹ si ni lati ṣe nkan ti yio wu awọn enia yepirẹ.

Ogbẹni Dimbleby ni on mọ bi o ti ṣe ni taiyan lati mọ idi bi ọrọ gbogbohun ti nṣiṣẹ.

(Wo Yoku Ni Oju Ewe Kerin)

AWON OJOGBON ONISE-GUN EHIN FI YE WA WIPE

BI A BA NFI EGBOGI






COLGATE DENTAL CREAM FO EHIN

KO NI JEKI EHIN ENI BAJE, O DARA PUPO



Iṣẹ ti Egbogi yi nṣe ni wipe, eyiti o nho bi oṣe yen, yio wọ gbogbo pala-pala ehin, yio si yọ gbogbo ajẹsi kuro, ko ni jẹki enu run, ko si ni jẹki ehin bajẹ.




O njeki ehin funfun, enu ko si ni run mo.

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI - QFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VIII. NO. 455. LAGOS, SATURDAY FEB. 18, 1956.


## Ere Eyo Adamu-Orisa Nilu Eko

Ni ọjọ Alamisi ijẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ti Alaiyeluwa ọba obinrin ati ọlọlajulọ ọkọ rẹ fi ilu wa Nigeria yi silẹ, ti ọkọ wọn ṣi kuro nilu Eko ni a ṣe ere Ẹyọ Adamuorișa fi ṣe ẹyẹ sin awọn ẹni-aiye - ẹfẹ na s'ọna.

Ni idaji owurọ kutu - hai, ni a wo Hu - ha-ha ti gbode kan ka kiri gbogbo ilu ti tọmọde ati agba nsare jade lati inu ile wọn lati fi oju ri Agogoro Ẹyọ

Ohun to jẹ pataki julọ ni tito ti awọn Ẹyọ to si oju ọpọpo - ọna lọtun ati losi, lati Ẹhingbẹti de idi Kereni nla (Carter Bridge) ni Idumọta ti gbogbo wọn si nfi Hu - ha - ha da gbere fun Alaiyeluwa ọba obinrin pẹlu ọlọlajulọ ọkọ rẹ wipe o digba oṣe. !

Esurukuru, alafia ni ẹ o dele. !

### ẸYỌ TI A Ș GBẸHIN

Ere Ẹyọ Adamuorișa ti a ṣe gbẹhin ni eyiti a fi sinku o'ogbe Ọba Falolu ni oṣu march ti ọdun 1952. Ẹyiti a si ṣe ni ijẹta yi ni ti isinku ẹni-nla wa ologbe oloye nla Sir Adeyẹmọ Alakija-Baba Eko, nigba ọjọ rere aiye rẹ, yio si tun jẹ iranti ọjọ ti Alaiyeluwa Ọba obinrin ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ fi ilu Eko silẹ pada si ilu oyinbo.

AGOGORO ẸYỌ Hu-ha-ha.


## Ma Wo Sinima Ninu Ile Re



Ẹrọ Sinima To Gbadun Gbogbo Irin'ṣẹ Rẹ Ni O Ye Koro Pẹlu Itanṣan Ina To Mọlẹ O Nfi Atupa Lẹtiriki Șișẹ. Ma Gbadun Sinima Ati awọn Irawọ Rẹ Ti Yio Ma Yi, Yio Ma Dara Ati Ijo Pẹlu Agbara Ayika 35 mm. Ao Fi Ile Rẹ To GUN Ni ẸSẸ 55. Ranṣẹ L'ọ Fẹ.

Eyi Ti O Dara Julọ £3. 0. 0. Awọn Ile Rẹ Nikan Elẹṣẹ Mẹfa 6/ E Fi Owo Ranṣẹ Patapata. Ko Si Awin.
NATIONAL NOVELTIES (205), BULANSHARA, (U.P.) INDIA

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko chin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2½d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


## ỌKỌ OGUN FI EKO SILẸ

Ọkọ ogun nla ti a npe ni H.MS. "Magpie" ti o ti de si Ebute Eko lati igbati Ọba obinrin ilu oyinbo ti wọ ilẹ yi ni ọkọ ogun na fi ilu Eko silẹ pada lọ si Takoradi nilu awọn Aganyin (Gold Coast) ni ọjọ Satide ti o kọja.

Ọkọ Ogun yi de si Ebute Eko ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu January, 1956, fun ti iyẹsi ib ẹwo Alaiyeluwa Ọba obinrin ati ọlọlajulọ ọkọ rẹ ọkọ ogun na dakan de Ebute Pọta Koti nigbati ọba lọ bẹ ilu ila-orun wo.

O și ku nkan bi wakati mẹta ti ọkọ ogun 'Magpie' yi yio și ni Ebute Eko, ni ọkọ ogun ti a npe ni H. M. S. "Sparrow" de wa ba ki awọn ọkọ ogun mejeji to și kuro ni Ebute Eko ni dede agogo meji ọsan dori-kọ ọna Takoradi.

Ni Takoradi ni ọkọ ogun H. M. S. "Sparrow" ti ọgbẹni Newman nṣe ọga'kọ rẹ, yio ti mu ọna ilu Oyinbo pọn, ti Ọkọ-ogun H.M.S. "Magpie" yio si mu ọna ibudo rẹ pọn nilu South Africa.

Alafia ni o ba de sihin, alafia ni o si fi pada lọ. Ogo ni fun Baba l'oke orun

## Omo Ilewe Fun Oba Obinrin Ni Iwe To Ko

BENIN.—Ni ọjọ Alamisi ọsẹ tokọja ni ọmọde-kunrin ọmọ bi ọmọ ọdun mẹtala ti o jẹ ọmọ ilewe nilu Warri ni Ọlọpa Ọba ta mu ti nwọn si da duro si Ṣọbu awọn ọlọpa (Police Station) fun ẹsun wipe o fi iwe ti o kọ fun Ọba obinrin ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ.

Gbara ti ọkọ ofurufu gun'lẹ si ibudo rẹ ti Oba obinrin pẹlu Ọlọlajulọ ọkọ rẹ nlọ ninu Moto ayọkẹlẹ ti a și ori rẹ silẹ fun ki ẹnikẹni leri awọn ala yẹ na, bẹni ọmọde ti orukọ rẹ njẹ Henry Aghehowa sare jade larin awọn ọmọ ilewe ẹlẹgbẹ rẹ ti o si nna iwe ti o kọ (letter) si Ọba obinrin ni Ọlọla nla ọkọ rẹ ba gba iwe na lọwọ rẹ.

Nigbati awọn ọlọpa da ọmọ na silẹ ni ọjọ Monday, ọjọ kẹtala oṣu yi, gbolohun ti ọmọde'kunrin na sọ nipe inu on dun gẹgẹbi awọn ti da on silẹ, ṣugbọn on și ni ireti si iwe ti on kọ si ọba obinrin wipe yio șe iranlọwọ fun on.

## IROHIN ILU OYINBO

(Obẹrẹ ni oju ewe kẹta)

Ninu ki a ma fo ninu ọkọ ofurufu ni agbara rẹ gbe fara-han julọ. Ni ọna yi papa o ti fi ifẹ rẹ se ajo fun rere awọn enia. Nigbati o mba awọn ẹgbẹ ọkọ ofurufu sọrọ ni igbakan o fi ye wọn wipe gẹgẹbi ọmọde ṣe ma fi ere șire, ni o nwu on lati fo ninu ọkọ ofurufu nigbati on wa ni kekere. Lọnakeji o ni on mọ wipe nibiti ero ilọsiwaju ba gbe so awọn enia pọ, ifẹ ati oju rere a ma ru soke, ati bi o ti jẹ wipe ọrọ yi șe si awọn ti o nfo ni ofurufu, wọn lara, bi on ba nkọ lati fo ninu ọkọ ofurufu, on yio le mọ riri ișoro ati ohun ti o ye awọn yioku.

### O KỌ LATI NINU AFẸFẸ

Biotilẹjẹwipe ọpọlọpọ ni o tako oloye Edinburgh, o tẹsiwa-ju lati kọ bi a șe dari ọkọ balu ninu afẹfẹ.

O jẹ ọkan ninu awọn oluwadi ti wọn mọ ilo ọkọ ofurufu ti a npe ni "helicopter" bi o șe nmu irin ati isẹ ya. Nigba ọpọlọpọ ti o ba wu ni ima gbe ọkọ ofurufu rẹ yi ba si ọgba ti o wa ni afin iyawo rẹ.

O ni idi ti o nșe gbogbo nkan wọnyi, ki ișe fun idaraya tabi awada. Gẹgẹbi ipo rẹ o nilati ni iriri, o si nilati ni imọ ijinlẹ nipa ọrọ ti o ba nșe nigbagbogbo.

## Jamba moto Akeru Sele

Awọn ero marun ati Awa-moto l'o rọrun nigbati moto Akeru kan lọ fori sọ igi nitosi UDI lọna Enugu silu Onisha.

Agbọ wipe ni ọjọ Monday ni nwọn to ri oku wọn gbe nigb-ati nwọn nko apo Simenti to bo wọn mọlẹ, ti moto na nko lọ silu Onitsha.

Nwọn si ko oku wọn lọ sile ayẹwo (Mortuary) ni Enugu.

Ki Oluwa majẹ ki aria ni ọjọ ti obi np'ọna.


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 393) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN

## ẸKU ABỌ O, ALAFIA KI Ẹ DE BI?

Gbakẹ ni ari ọgbẹni wa, Raji Moṣebọlatan ọkan ninu awọn aṣoju iwe Irohin wa nilu Abidjan, Adjeme; ni Oke Okun, ti dakẹn wa bẹ ilu rẹ wo.

Ọgbẹni Raji Moṣebọlatan yi jẹ ọmọ ilu Ejigbo nitosi ilu Ẹdẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun (Western Nigeria) Onișowo pataki ni iṣẹ, ọmọluwabi enia si ni. O fi ọsẹ kan bẹ ile iṣẹ Iwe Irohin wa Eleti Ọfẹ wo ki o to rekọja lọ si ilu rẹ.

Alafia ni ẹ o dele o.


## Kere o!

A ti ni orișirisi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



## Enjoy Your Own —Songs—

Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . . THROUGHOUT . . . . . . . . . . NIGERIA . . .**


## E Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe




Awon Onise Owo Feran Siga CAPSTAN Orun Re Lo Dara Ju



## Awon Dokita Fi Han Wipe

### Ose Palmolive Le Jeki Ara Re Dan Ki o si Jolo Larin Ojo Merinla



Ara Mi Dan, O Si Jolo Nitoripe Mo Tele Ilana Ti Awon Dokita Se

Ibo Ohun Ti Iwo Yio Se Niyi:-
1. Fi Ose Palmolive we Oju re
2. Fi hiho re pa Oju re Fun Iseju Kan
3. Fi Omi nu kuro. Se be ni igba Meta l'ojumo fun Ojo Merinla




EPO ILẸ AFRIKA NI A FI SE ỌṢẸ YI.

GOLCATE PALMOLIVE L'OṢẸ


## PUBLIC NOTICE

It is hereby notified that the Idudua ceremonies and plays known as Agu'Osa will take place at the Palace grounds from 19. 2. 56 to 26. 2. 56.

AKENZUA II,
ỌBA OF BENIN.

## Iwa Anikan Jopon Npania (Apa Keji)

Lati Owọ Ẹsọ Ikoyi

Gẹgẹbi itan ti a ti sọ siwaju wipe iwa anikanjẹ ko dara, o nṣeku pa enia. Bayi bakanna ni oda ifa ti a npe ni Ogbe wọnrin tun jẹri si wipe ko nṣe iwa ti o dara. Iru ẹrọ yi ni awọn baba wa ni lọkan wọn nigbakigba ti aja-kalẹ arun ba bẹ silẹ, tabi iku ọwọwọ, nwọn o maṣe itọsẹ ọrọ tabi ki nwọn ma wadi kini aṣiṣe na ti nwọn ṣe ki o to fa iru ajalu bayi jade. Igbagbọ wọn ni wipe iru ohun bawọnni ko ni ṣẹlẹ lasan bi ko ba nidi, boya o le jẹ ẹsan fun aṣiṣẹ na ti a ti ṣe. Njẹ gbọ bi odu ifa yi ti tun wi:-

A jẹ a ko fun ẹlẹru jẹ, A mu ako fun ẹlẹru mu
Ẹ ko ri i nigbati a se Ọṣọṣọ ẹpa, ti a ko fun ẹlẹru jẹ Ti a ko fun ẹlẹru mu Ti ẹlẹru wa gun ẹsẹ sọna de ni ? Ogbe wọnrin.

Nigba atijọ, ni le Ifẹ nigbati ọdun ba jọ ti gbogbo ilu ba ṣe ase repẹtẹ ti nwọn njo ti nwọn nyọ fun ti ọdun titun, kiki ọmọ ibilẹ Ifẹ nikan ṣoṣo lo mba wọn ṣe ajọyọ na. Ẹru ko gbọdọ jade ba wọn ṣe. Ẹlẹru kan ko gbọdọ ba wọn jẹ tabi ki o ba wọn mu. Awọn ọmọ Ifẹ yio ṣe awọn ẹru wọn mọ inu ile fun ọjọ meje, nwọn ko si nfun awọn ẹru ti nwọn se mọ inu ile wọnyi li onjẹ, nipa bayi, ọpọlọ awọn ẹru ati alejo ti nwọn ti mọle li o nku danu ki ọjọ meje to pe nitori nwọn ko ri onjẹ jẹ. Ọpọ awọn ẹru lo ma nku bayi lọdọdun. Awọn ọmọ Ifẹ rope awọn njaiye ọmọ Onilẹ nipa bayi.

Adanilọro lo sa nfi agbara kọni. Lẹhin ọpọlọpọ ọdun, awọn ẹru nwọn yi wa gbọn, nwọn p e r o p ọ, nigbati ọjọ ati ṣe ọdun wọn na ku sata, nwọn l ọ ṣ e egbogi oloro kan ti o jẹ wipe ẹnikẹni ti o ba tẹ egbogi na mọlẹ daju da u ọrun lẹrọ. Nwọn lọ ni oru si nu igbo mọlẹ nibiti awọn ọmọ ibilẹ Ifẹ gbe m a nṣe ajọyọ na fun ọjọ meje.

Nigbati ọjọ ko, awọn ọmọ ibilẹ Ifẹ gẹgẹbi i ṣ e wọn tun lọ ti awọn ẹru wọn mọle, gbogbo awọn ti o lọ sibi ayọ na, ọkan ko pada bọ laye bayi ni awọn ẹru nṣe lọdọdun tobẹ ti awọn ọmọ Ifẹ ko le ṣe ọdun na mọ. Nigbati gbogbo ilu fẹrẹ parun tan ni awọn ti o ku tọ Ọrumila lọ wipe ọdun ajọyọ wọn lo mbọ yi, kini awọn yio ṣe ki o ma si iku lọ'na.

Ọrumila jan Iporun rẹ mọlẹ, o ri Ogbe-wọnrin Ọrumila ki odu Ifa na gẹgẹbi a ti kii soke yi, o wipe bi nwọn ba nfẹ ki iku dawọ duro tẹru tọmọ, tonile talejo ni ko jijọ ṣe ọdun na. Ayani, o ri i, nigbati tẹru tọmọ jijọ ṣe ọdun ti nwọn jẹ ti nwọn mu ti ko si iku lati ọjọ na wa ni tẹru tọmọ ti njijọ ṣe ọdun na

Ọrumila ni Ajambete, mo ni Ajambete
Oni muwa - muwa lapa eiyele ndu
Mesewa - mesewa laparo ndun
A difa fun gbogbo igi oko
Lọjọ ti nwọn nko ese lọ si ọrun
Ti Igi ọpẹ yio ma ṣanri tọ wọn lẹhin. Irosu sa




## Oku Olomo Ase Isetan

Ni ọjọ 23 Dec, 1955 Iya wa Jinatu Mọbọlaji Ankẹ, Ọmọ Ọba Alashoko Oloyede fi aiye silẹ lọ si ile, Iku iya wa dun wa pupọ, nitori pe o fi wa sile, o si dun mọ wa lọpọlọpọ nitoripe o di arugbo ko to fi aiye silẹ, Nko ba sọ ọjọ ibi iya wa a wo iwe a ko, ri nitoripe o ti pẹ ju. Akọbi jẹ ọkunrin o di ẹni Adọta ọdun ki iya to ku Ẹnyin ọkawe ẹjẹ ki aṣe adura ka si ṣe amin, pe ki a gbo laiye bi igi nla, ki a si ma rẹ danu ni ọjọ aipẹ ẹ ba mi ṣe Amin

Orukọ a k ọ b i Yesufu Akande a ṣe oku yi ni 30th January 1956, gẹgẹbi aṣa awa Musulumi ni ilu Tiassale ni Cote de Ivoire. Ni owurọ ọjọ yi Alaji wa, Baba wa, Ashifatu Ọmọ ibilẹ Ogbomọshọ, oke Mosifa, awọn ni wọn ṣe Nasia fun, wa awọn Alaji ti wọn wa wa pẹlu wọn ni Alaji Salami Opẹloyẹru. Alhaji Salami Alẹṣinlọyẹ, Alhaji Adiatu, Alaji Gbadamọsi, Alaji Raimi, ati awọn miran ti a kole ma daruko ninu wọn to ti Abidjan wa bani ṣe ariya ọjọ yi.

Arẹmọ o k u k i awọn Janmọh ọkunrin ati Janmọh obinrin to wa ṣeliu Tiassale, ẹku inawo, o si tun k i a w ọ n Janmọh Adjeme, awa tajẹ Janmọh Tiassale orukọ wa ni wọnyi: Alaji S.O. Oloyede, Alufa Jinadu Ojo, Jimoh Oyetunde, Raji Alade, Tujani Ṣewu, Amusa A l a d e, Karimu Oyelaran, Sani ọmọ Ogunro, ati awọn obinrin wọn.

Awọn wọnyi ni awọn ara wa Ọmọ ibilẹ Ishoko, awọn ara wa ti wọn jẹ Ọmọ ibilẹ Ọlla ni awọn bi Benjaman Ajao, Jonathan Fasẹsan Josaieh Adewuyi, Sadiku Simion Oyelani, D a v i d Oyebile, Alufa Ilọrin, Tijani Ejigbo, Lamidi ọmọ Iwo, Sule, Peter Ọladokun ati Awọn miran Oku Iya wa dun O larinrin, wọn ṣe inawo pupọ-pupọ Iyin ko amoju ba.

Lati Owọ A l a j i S.O. Oloyede Tiassale,

## Ibere Oro

Olotu,

Inu mi yio dun ti ẹba le fi aye gba mi lati ṣe ibere ọrọ yi lọwọ a w ọ n ọkawe wa. Awọn baba wa ni ma pa lowe wipe:- "Bere - bere ki ṣ i bere ati wipe oyẹ ki awa idi ohun gbogbo daju nitoripe ọgbọn ọlọgbọn ni ki je ki a pe agba ni were.

Awọn ohun mẹta n a n i:" Ori - rere, Inu-rere, ati Ọrọ-rere". Ninu awọn ohun mẹta nwọnyi mo f ẹ m ọ eyiti o y ẹ ki enia ni ti y i o bori a w ọ n meji ti oku.

Inu mi yio dun t i a w ọ n Ọkawe wa ba le dahun ibere yi laipẹ.

Emi ni
TOFF SOLOMON
(Anishere Ogun nile)

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti- Ofe

## WESTERN REGION Production Development Board

ACHITECTS

The Board invites suitably qualified Architects practising in the Western Region and Lagos who may wish to be considered for Board work in the future.

Applicants must state their qualifications and experience and address their applications on sealed envelopes, marked "Architect" in the bottom left-hand corner of the envelope, to reach t h e undersigned 29th February, 1956.

E. A. AJAYI
CHIEF ENGINEER
Western Region Production Development Board

## Oba Gesi Ni Ilu Ibadan

Lati ọjọ ti Alaiyeluwa Ọba obinrin ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ ti ba ọkọ-ilẹ Raluwe de ilu Ibadan ni ọkankejọkan irohin ariya alarinrin ti gbojikan kakiri gbogbo ilu Nigeria ati awọn ilu okere miran.

Koṣerọ ni iwe iyẹsi ti Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ ti iṣe Alakoso Ijọba Iwọ-orun ka fun Alaiyeluwa Ọba obinrin ti ẹni-aiye-nfẹ Alaiyeluwa Ọba na si f'esi si ni isọri-isọri ọrọ to mbẹ ninu iwe iyẹsi na



Bẹna si ni orişirişi ere iyẹsi to gbadun ti wọn fi şe ẹyẹ fun Ọba ko şe ka tan, ti o fi kan ere ijo awọn Onişango; awọn obinrin arugbo enia ti ọjọ ori wọn ti le ni adọrin ọdun wa jo ijo ọla kan ti irufẹ ijo bẹ fẹrẹ ndi ohun igbagbe larin awa ọmọ ode oni, eyi nikan kọ, Timi Ọba Ẹdẹ tun mu ilu abalaiye kan wa fi şe ẹyẹ fun Alaiyeluwa ọba obinrin ti o jẹ wipe bi awọn ba fi ilu na sọrọ, kia ni awọn ti o ran nişẹ to wa ni okere diẹ si wọn yio gbọ ti wọn a si şe gẹgẹbi ilu na ti wi.

Eyi ya alaiyeluwa Ọba obinrin l'ẹnu pẹlu Ọlọ'aju ọ ọkọ rẹ, ki a ma d'ena p'ẹnu ilu Ibadan ndun yungba ni. Diẹ ninu awọn ẹni-ọla to di opo Ijọba Iwọ-orun mu ni aworan wọn wa ninu iwe wa ti ẹ nwo yi.

Ọba Alake ti ilu Abeokuta ati Ọba Ọni ti Ile-Ifẹ ni Alaiyeluwa Ọba obinrin fun ni Ida oye nla ti e ti fi da wọn l'ọla

## IBERE ORO

OLOTU,

Jọwọ gbami laiye lati bere ọrọ yi lọwọ awọn ọkawe rẹ, Eleti-Ọfẹ ẹniti oye ọrọ na baye, ki o jọwọ ki o fi ye mi.

Ede ti awọn oyinbo ma nsọ fun awa alawọdudu wipe "Ki a pada si aşa ilẹ wa" (Back to the land) ọrọ na ko ye mi. Emi fẹ mọ ọna ti a fi le pada si aşa ilẹ wa, ki ẹniti o ba m'ọna fi han mi o,

Emi ni
Y. SULE
Babalawo, Igbodu
Ilorin


## Irora Ibadi

Egbogi ti a şe fun niyi:-
Nigbuti ibaradi ba ndun ni, oluwu rẹ nfẹ itoju bi a ko ba tete fi egbogi rẹ ko loju, aisan yi a ma fa Ẹhin-didun. Lakuregbe, Wodi-wodi, Akọ Ẹsanri ati Igunfẹ-buruku wa.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba şişẹ tara, şugbọn bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio de si oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti şişẹ. Danwo lọ ra ni şobu egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles


## O mu yan yan yan

Kosi botiri ni orun ọdun ni o mu yan yan yan 'oinu. O fẹrẹ le ma ta pu, pu, pu, bi igbati enia ba nyan agbado gbugburu l'ori ina.

Nigbati orun mu bayi ni aiko ẹrun ti ọdun ni, niẹ bawo ni asiko ojo yio tiri nigbati o ba to asiko ti ojo yio bẹrẹ işẹ tirẹ

Ohun gbogbo nşişẹ fun rere ni a si ni igbagbọ wipe Ọba Olodumare Ọba Ọga Ogo yio jẹ ki orun na şe anfani fun gbogbo kari o,


Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe


No. 42

## Federal Medical Services

VACANCIES FOR STUDENT NURSES OR MIDWIVES

Applications are invited from girls with General Schools Certificate, Middle IV, Secondary Class III or IV Certificate or Modern II Certificate for training as Nurses or Midwives. Preference will be given to candidates of School Certificate Standard.

2. Those who are accepted will enter the Nurses Preliminary Training School, Lagos for a 6 month's course which will commence in April 1956. During this course, Students will be required to reside in a Gorvernment Hostel or in an approved lodging house. A subsistence allowance at the rate of £7 a month will be payable and where maintenance is provided a charge of approximately £4 a month will be made.

3. On completion of this Preliminary course, successful students will be appionted as Probationer Nurses or Pupil Midwives in the salary scale N. 1 which commences at £150 a year. They will be posted either to the General Hospital, Lagos for training in General Nursing or to the Massey Street Maternity Hospital, Lagos for training in Midwifery.

4. Candidates are required to forward the following documents with their applications which should reach the PRINCIPAL MATRON, FEDERAL MEDICAL HEADQUARTERS, LAGOS on or before the 25th February, 1956.

(i) Copy of Certificate of Education.
(ii) Copy of Birth Certificate or of a Sworn Declaration of age made by Parent or Guardian.
(iii) Copies of 3 recent testmonials, one of which should be from the Headmaster of the last school attended or from the most recent employer.

5. Only those candidates who are selected from interview will receive a reply.

# Ilu Ibadan Gba Oba Elizabeth Keji L'alejo

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

ọna ara fun awọn ọmọ Ọba lọkunrin lobinrin ati apoti ti a fi atata igi ilẹ wa gbẹ gbamuṣe.

Ni ọjọ isimi ni Ọba na ati Ọkọ rẹ lọ jọsin ni ile Ọlọrun ti C.M.S ni Okebọla, Ibadan, isin na ni ede Yoruba ati ti Gẹsi larinrin lọpọlọpọ, orin ndun yungba- yungba, Olori Alufa A. B Akinyẹle si ṣe iwasu to wu enia lori pupọ. Ni ọjọ Monday ni paripari waiye ni ọdan, Ibadan nibiti ẹgbẹ-gbẹrun ọmọ ilewe ati awọn to ti jagun ri pẹlu awọn Girls Guids, Boy scouts, Brigades pejọ lati ki Ọba kabọ. Nitotọ kiki na pọ to bẹ gẹ ti mimi rẹ fẹrẹ le de ode ọrun, gbogbo ohun lo si nke "Kabọ" "Ka" "Kabọ"

Ọba Elizabeth, kabọ, de ipo pe ọrun fẹrẹ le faya. A mu awọn saraki- saraki wa si iwaju rẹ, o si gba wọn lọwọ, ninu wọn si ni ogbẹni Mọmọh, Tewe alufa W. A. Mellor ọgbẹni L. J. Dosunmu. E. O, Alayande, ọgbẹni S. A. Balogun, E. A. Ogunṣola, alufa agba S. I Kalẹ, Iya afin A A Ademola, ẹgbẹni T. L, Oyesina, ọgbẹni J. O, Lanlyọnu, Iya afin S. A. Banjo, ogbeni J. S. O. Ogunnaike ati ọgbẹni N. O. Faliyi.

Lẹhin na ni Ọba ati Bale rẹ wọ ọkọ yika gbogbo awọn ogunlogọ ọmọ ilewe lati ki wọn fun ẹyẹ ọjọ na, irohin ko si to afojuba. Lẹhin eleyi ni oba wa lọ si oko o ba ni odo ọna nibiti on ati ọkọ rẹ gbe ri gbogbo orişirişi ohun ọgbẹni ati ẹranko bi Ẹlẹdẹ, Aguntan, ati Ewurẹ, Pataki ninu awọn to pe si bẹ ni ọlọla Kọla Balogun, ọlọla A. M. A. Akinloye ati awọn ọga osişe ibẹ, bi ibẹ si ti jinna si igboro to bẹni ero pọ pupọ nibẹ. Ni irọlẹ ọjọ yi ni aşọ ibilẹ npe aşọ nranşẹ lara ọba, Ijoye, gbajumọ ilu lori oke agodi nibiti ọba de si, o si yin pupọ. Ọba ati ọkọ rẹ nmu nyọ larin gbogbo enia, ko si si ẹniti o ma ni on ko gbadun ipa na.

Li alẹ ọjọ yi ni asi fi ina jombela dabira loju sanma. Ni ọjọ Tuesday lọjọ ti ile ẹkọ giga nibiti agbe fi aşe da Ọba lọla, ibẹ si minringindi pẹlu ni alẹ ni aşe ti Ijọba Ipinlẹ gbẹrẹgẹrijẹ fun Ọba, lẹhin eyi ni awọn ijọ Alarabara wa gbode kan, o dun pupọ ju.

Ni ọjọ Wednesday ni a si Gbongan titun ti a kọ fun Ipinlẹ Iwọ - Orun (at £370,000) ti a si pari rẹ larin ọdun kan pẹlu awọn oşişẹ ile wa. Irohin ko to afojuba, awọn pataki-pataki po lo su bi eşu ninu aşọ nlanla inu Ọba ati Oko rẹ si dun si apejo yi, lẹhin eyi ni Ọba fi oye oye da awon to şe wahala fun gbogbo eto ayesi rẹ lọla. Gomina Ibilẹ ati Ogbeni Morrison ti Information Services wa ninu won.

Lẹhin eyi lo ki Ibadan pe o digba, o si wo inu Ayokele rẹ nlo larin ogunlogo enia to ti pejo si otun ati osi.

Ni gbogbo igba to wa ni Ibadan, iwa irẹlẹ, ọyaya ati ifẹ si gbogbo enia han gidigidi ninu Ọba yi ati ọkọ rẹ, awọn si ti fi ti Ọlọrun şaju ninu gbobo irin ajo wọn, nitori gbogbo ilu ti wọn sun ninu re lo fẹ jẹ wipe wọn lọ jọsin ninu ile isin-ẹsin ilu wọn.

Lati Ibadan de ilẹ Ijẹbu Ode ni ero nwọ bi omi pẹlu ilu asia ati aşọ oniyebiye lati fi ki Ọba yi kabọ, nigbati o de Ijẹbu Ode ati Şagamu ni on papa wa ri agbayanu aşọ ilẹ Yoruba to jinna haunhaun, iyẹsi na si pọ pupọ ju ohun ti ẹnu nikan le sọ.

## Oba Obinrin Nilu Kano

KANO. Nigbati Ọkọ Ofurufu ti a npe ni "Atalanta" to gbe Oba wa silu Nigeria da gbe Ọba Obinrin ati Ọlọla nlu Ọkọ rẹ de ilu Kano ni ọjọ Alamisi (Thursday) ti işe ọjọ kẹrindinlọgbọn oşu February yi ni dede agogo mẹji ọsan, ki o wa wo bi ina orun to mu yanyan ti mbu enia lara jẹ. Nwọn tiẹ sọ wipe orun ti yọ lati dede agogo mẹfa owurọ kutu ni.

Ariwo nla gee l'ẹnu awọn gambari bayi wipe Ra ka dede! Ranka dede! eyi ni o jẹ gbolohun ọrọ ti awọn ọmọ alahusa fi nki Alaiyeluwa Oba Obinrinati Ọlọlajulọ Ọkọ rẹ ni ibodo Ọkọ Ofurufu nilu Kano.

Awọn enia to s'ọtun-s'osi ọna ti Alaiyeluwa pẹlu Ọkọ yio gba fun ọpọlọpọ wakati laibikita fun orun ti o fẹrẹ le ma jo enia bi ina nitori ati le fi oju wọn ri awọn ẹni-aiye nfẹ na. Awọn ọmọ ilewe to tiwọn lọtọ, bẹnani awọn Ọlọpa ati awọn ọpọlọpọ oşişẹ iranlọwọ miran.

Polowo Ọja Re Sinu Iwe Eleti-Ofe






## AGOGORO EYO



### Hu- Ha-Ha Ha

Aworan ọkan ninu awọn Ogunlọgọ Ẹyọ to fi aropalẹ (Aşọ isanmọdi) dabira nigboro ilu Eko ni ọjọ Alamisi (Thursday) ti Alaiyeluwa Ọba Gẹsi ati Ọlọlajulọ Ọkọ rẹ fi Ilu Eko silẹ niyi.


## Notice to Building Contractors

WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

The Board proposes to erect a number of Buildings during the financial year 1956-57.

Contractors wishing to tender for any or all of this work are asked to notify the Secretary, Western Region Production Development Board, Ibadan, by letter not later than noon on Wednesday the 29th of February, 1956.

Replies should include information regarding the experience of the applicant, the extent of his business and should be accompanied by a Banker's Reference.


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos